# LEHIN OGORUN ODUN, ORORI MARTIN YIPO PADA




ELETI OFẸ
A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO




VOL. IX No. 537. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, SEPTEMBER 14, 1957 KỌBỌ MEJI (2)

## Ejo Mba Enia Gbe'le Po Nilu Eko, Eyi Ara!

EKO. Irohin ti a ri gbọ ni wipe nigbati awọn ti o nwo ile fun atunṣe arin ilu Eko wo ile Pẹtẹsi nla kan ni Breadfruit Street, lọjọ kan ninu ọsẹ yi, awọn ri ejo nla kan pa ninu ile na, awọn si ba ẹyin ti ejo na ti yin nibẹ pẹlu.

Eyi jẹ ohun iyanu pupọ lati gbọ wipe ejo ati awọn enia jijọ ngbe inu ile kanna pọ fun ọdun gbọrọ laisi ewu tabi jamba larin wọn.

A gbọ wipe awọn enia ti o ngbe inu ile na ko fi oju wọn ri ejo na ri bẹni inu ile kanna ni awọn ngbe. Ohun ti ako le sọ ni wipe boya awọn Oloriṣa Ogun ti nwọn ma ngbe ejo fi ṣe agbe tabi bara kakiri ilu ti mba wọn gbe inu ile na ri.

Ohun iyanu ko ntan laiye.




**THE NATIONAL BANK**
**Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital - £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO; BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Lehin Ogorun odun, orori Martin yipo pada

EKO. Oju Orori, tabi ibiti nwọn sin oku Ologbe Daddy Ojo Martins si ni oju opopo ita Martin nilu Eko, ni igbimọ L. E. D. B. gbe kuro ni nibiti o wa lọ si Garber Square, nita Akanni, niwaju ile Ọgbẹni Dokita Maja.

Awọn opitan sọ wipe, ibiti oju Orori na wa nisisiyi jẹ arin iyara Daddy Ojo Martins, ohun ti o jẹki

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)

## Ifihan awon nkan ile Nigeria



Ọmọbinrin ti o gbe ilu Apọnran dani ti a nwo ninu aworan yi jẹ ọmọ ilu Ilesha, ti oruko rẹ njẹ Omidan Ọlayide Olooyẹmi, o nfi ilu sọrọ lasiko igbati nwọn nṣe afihan awọn ohun iṣẹdalẹ ilẹ Yoruba nilu Oyinbo.

Ninu awọn ohun iṣẹdale na ti nwọn fi han ni, awọn ọja ati gele, ade ọba ti a fi ileke iyun ṣe ati awọn ere bi ti gelede.

Awọn olotu egbe British Council fi awọn aworan aṣọ agbada ti o dara ti a nwọ nilẹ Yoruba, eyiti o nṣe aṣọ iṣẹdalẹ han ati aworan ọba Bini ninu aṣọ ti o wọ nigbati ọba obinrin fi wa bẹ ilu wa wo.

# Alapara Ibadan nki yin o

OKE FỌKỌ
Ibadan

Jọwọ awe, bi o ba nfẹ idẹra owo yiya ki o lọ si ilu ti wọn npe ni Ile-Oluji. Yala o fẹ gbe iyawo tuntun ni tabi o fẹ gba iyawo aladugbo rẹ ni ti o fẹ sanwo rẹ ni kotu. Boya o fẹ ya owo ṣe ẹsọ lati ra mọto ni tabi o fẹ san owo oṣiṣẹ oko rẹ ni. Ni Ile-Oluji, iṣẹ owo yiya san ju owo koko (Cocoa) lọ.

Ni aipẹ yi ti mo de ilu na mo ka awọn ti o nya ni lowo, wọn nlọ bi igba enia tabi igba ẹgbẹ. Bi o ba de ibi wa ri orukọ bayi Arowosọ Olowoele, Orisunbare Olowoele, Ajanlekoko Olowoele, Bọdaowa Olowoele, Bosere Olowoele ati bẹbẹ lọ tit. Awe, Ile-Oluji ni Ondo ma dun gbe o. Ilu a ya wọn lowo tọkẹ-tọkẹ. Ẹ ya mi lowo ki nfi gbe iyawo tuntun, ele ori rẹ ni nko le san.

Amodi Ayọkẹlẹ

Mo ro wipe ariran ni Ọgbẹni Ọnatade ti o kọwe sinu Eleti-Ọfẹ ni aipẹ ti o wipe o dabi ẹnipe aiye fẹ parẹ. Ẹ ka iwe na, Olotu,

Nitotọ mo fi ara mọ iwe ti Ọgbẹni Ọla Ọnatade kọ sinu iwe Eleti Ọfẹ wipe o dabi ẹnipe aiye fẹ parun nipa "werepe oloro" ti awọn alagbara ile aiye nda si afẹfẹ kakiri ti a npe ni atomic bọnbu (Bomb).

Imale sọrọ ojo ku, Lẹmọmu ni Ọlọrun jẹri on, Ko pẹ ti Ọgbẹni Ọnatade sọrọ yi ni amodi lukuluku bẹrẹ kakiri gbogbo aiye. Amodi lukuluku na ni a npe ni Nfulẹnsa tabi awọn alaiye ti npe? Ẹniti o ba ri ti odun mọkandinlogoji sẹ hin, a mọ wipe wẹrẹ-wẹrẹ ni amodi na npa enia.

Awọn Onigbagbọ ati Imale ni ina nla ni Ọlọrun a fi pa aiye run. mo ṣe bi awa ara aiye na ni ao fi ọwọ wa da ina na.

Olotu, nitotọ, o dabi ẹni pe aiye fẹ parun o.

Emi ni,
Aiyekotitọ

Ko nṣe ọrọ yẹyẹ-aiye fẹ parẹ nitotọ. Amodi Ayọkẹlẹ ko mọ ọmọde ile ko mọ agba Eko. Ko mọ Wundia Ọfin, ko mọ Abileko Ẹhin ogba. Ko mọ arugbo Isalẹ jẹbu, ko mọ Ọlọmọge Ofin Fọkọ. o ti nkọlu O owo ... o nfi inu talaka ṣere. O kọlu elelubu ọja Ayẹyẹ, a ko ri elubọ fi jẹ gbẹgiri mọ.

Bi emi Alapara ti nkọwe yi nṣe ni mo ngbọn tọwọ-tọwọ ati ẹnu, bi mo ti nṣe ikun ni imu beni ori nfọ mi. Nṣe ni mo nrun ara mọlẹ ti mo wa njo ijo kan ti a njo nigbati mo nba wọn ṣe sanmọri ni ode Eko nigba atijọ ti nkọ orin bayi:-

yanki, yanki, ijo ti mo jo lana Gbogbo ara lo nro mi Ibadi ko jẹ temi, yanki. A jo fọwọ sori yanki.

Ẹniti o ba ri amodi ayọkẹlẹ ti ọdun mọkandilogoji ti o ji sẹhin sio awọn alagbara aiye ki wọn ma ma fi wa fun ogun mu

Ni ọdun 1918, bi a ṣẹṣẹ ti pari ogun Jamani ati awọn Gẹsi tan ni gudugbe fọ silẹ kakiri aiye. Adiẹ ko mọ ẹniti okuu on ni ọrọ na. Nko ni sọ itan na ni ọsẹ yi ṣugbọn Alapara ni ẹniti o ba ni agbalagba ti ọjọ ori rẹ to mẹdogun nigbana ko bere ọrọ itan na lọwọ wọn daradara. Nko wipe ki ẹ bere lọwọ awọn abileko igba Onjaburẹdi ati bofọwọkan-ọyan

Ọrọ pọ nibe - amodi ayọle ko dara lara o.

## Eiye Okin Ni Arewa Eiye

Ọkunrin ọdẹ aperin kan lo nṣe irohin nipa Eiyẹ kan ti a npe ni Ọkin. O sọ bayi wipe, awọn Ọkin ṣọwọn ninu ẹgan ilẹ Yoruba, ṣugbọn mo ba wọn pade nilẹ Baruba lọna Ṣaki. Idi rẹ ti awọn ṣe npe ni Ọkin ni wipe, iyẹ alarabara lo mbẹ lara rẹ, a ma rin nilẹ nigba miran bi ẹnipe o nyan, o si jọ ẹya bi eiyẹ Tolo-tolo.

(Wo iyoku loju ewe keje)

## Ipade ajodun gbogbo Scouts agbaiye



Nigbalasa kan ninu Warwickshire ninu Gesi, ni awon omo Scouts ti o le ni oke kan abo ti o wa si ajodun Jamboree lati orisa awon ilu metaleleogorin ti o nso ede Gesi gbe pa si. Ohun ti nwon se ajodun na le lori ni wipe o de ogorun odun ti a bi Ogbeni Lord Baden Powell Oludasile egbe Scouts ati Guide, o si di adota odun ti o da awon egbe mejeji sile.

Nigbati awon Scout ti o wa lati ilu Scotland nse idaraya, eyiti a nwo ninu aworan oke yi ni Scout ile Gambia kan ti o njo ni arin meji aworan yi.




# Railway Exhibition



Ninu awọn afihan ti awọn olotu ati alaṣẹ ọgba Reluwe ṣe laipẹ yi ni Teṣọn Iddo (Lagos Terminal) awọn fi han wipe gẹgẹbi ilu Eko ti atẹsiwaju ninu ilaju bẹni ayipada titun yio ma de sinu ile iṣẹ wọn.

Latijọ ina omi ati cedu lo ngbe ọkọ wọn sare loju irin gẹgẹbi eyiti a nwo yi ṣugbọn gẹgẹbi ilọsiwaju wọn, Ẹrọ ti o nfi ina mọna-mọna rin (Diesel Engine) ti ko njẹ eedu ni nwọn o bẹrẹ si lo.

Ẹrọ ti a nwo yi jẹ ọkan ninu eyiti nwọn ti nlo latijọ.

# Die ninu awọn ohun to sele ni odun 1927-28

1 Tijani Nọibi, ẹgbọn Lemọmu Ligali ṣalaisi ni ọjọ 4th oṣu Jan 1927.

2. Ni ọjọ 6th oṣu Jan 1927 ni ijọba kọkọ fiwe sode wipe nwọn o bẹrẹ si gbowo ori.

3. Awọn ẹgbẹ Ansarudeen ṣe ajọdun ọdun kẹta ti nwọn da ẹgbẹ na silẹ ni ọjọ 22nd oṣu Jan 1927.

4. Dokita Doherty, Dokita Manuwa ati Lọya Siffre ba ọkọ S.S. Wadai gunlẹ si ilu Eko lati ilu Oyinbo nibiti nwọn gbe lọ kọ iṣẹ ni ọjọ 26th oṣu March 1927

5. Stanley Robbin, ṣe ase nipa owo ifẹhinti ti yio bẹrẹ igba lọjọ 2nd oṣu June 1927 Sir Kitoyi Ajasa ni alaga ọjọ na, awọn isọnghe alaga ni Ọgbẹni T. Nelson Cole ati O Alakija. Stanly Robbin gba oye I.S.O ki o to ku.

6. Lọjọ 8th oṣu June 1927. ni Ọgbẹni Lawani Agbe Smith ṣalaisi nilu Oshogbo.

7 Lọjọ 10th oṣu June 1927 awọn Janmọ Musulumi ati Janmọ Alalukurani jijọ lọ kirun ọdun papọ. ṣugbọn Janmọ ti ijọ Alli Ballogun ati ti ijọ Ahmadiya lọ kirun tiwọn lọjọ keji.

8. Ọkẹ Ogidan, ti o nṣe iya ẹgbẹ awọn oloorin ọja ararọmi ṣalaisi ni ọjọ 12th oṣu June 1927.

9. Ọgbẹni Emanuel Makanju Awobiyi ti o nṣe Olotu Iwe Irohin Eko Igbehin ṣalaisi ni ọjọ 20th oṣu June 1927. 10 Ọgbẹni Ogunlana ṣalaisi lọjọ 7th July 1927

11 Ọgbẹni ISaac B Thomas di Olotu Iwe Irohin Akede Eko 15th July 1927

12 Disu Apata ṣalaisi lọjọ 24th Aug 1927

13 Marth K Ṣowumu ti o nṣe Iyawo Alufa Ṣowumi ṣalaisi ni 9th Sept. 1927

# Oro Oloye Akintola Nile Igbimo.

EKO. Oloye S L. Akintọla, ẹniti o ti nṣe Alatako ninu Igbimọ nla (House of Representatives) ti nwọn tun wa gbe ga si ipo Minister, lo sọrọ yi wipe:-



Iru oye ti nwọn jẹ loni yẹ ki o ni awuye wuye ti o ga, nitoripe, a ko ṣe iru ipade bayi ri pelu Ijoye Minister gegebi olori. Ọjọn ni ọjọ o ti yi jẹ fun wa, iye awa enia ti Ọlọrun dasi lati ri ọjọ oni yi, yẹ ki a ṣe ọpẹ gidigidi fun Ọlọrun, ki Ọlọrun si tun fun wa ni ẹmi gigun ati alafia ara ki ominira ti o mbọ ni ọdun 1960 le ṣ'oju ẹmi wa.

Oo ni igboiya lati sọ fun Oloye Prime Minister wipe, ki o maṣe foiya nipa awọn ọmọ ti o wa pelu rẹ ninu igbimọ yi, Prime Minister yio gbadun awọn ninu ibaṣepọ wọn.

Oloye Akintọla gba iyin gidigidi fun Alhaji Ahmadu, Sardauna Ṣokoto, ti o jẹ wipe nipa rẹ, ni a fi ri iru ọjọ oni. O sọ wipe, iṣẹ iwọsi patapata ni iṣẹ Prime Minister. E wa, ẹ jẹki a fi ara wa ṣe ọkan

(Wo yoku loju ewe kefa)

# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - ỌFẸ LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. IX. NO. 537. LAGOS, SATURDAY SEPT. 14, 1957


## Gbere Re, Tafawa Balewa!

Ọrọ ti Alakoso Ijọba Apapọ (Federal Prime Minister) so lori ọrọ Asọrọmagbesi wipe ijọba ipinlẹ kọkan wa fun ipinlẹ wọn, ijọba apapọ si wa fun ara re, nitoribẹ, kosi eyiti o le jẹ gaba lori ekeji ati pe ijọba apapọ ati awọn ijọba ipinlẹ ni lati ma fi ọwọ-wẹ-ọwọ ni ki alafia le wa ninu ijọba Nigeria.

Ọrọ ti Alakoso ijọba apapọ sọ yi dabi igbati enia si aṣọ lori Egungun ti gbogbo enia fi oju ri ẹbọra to wa ninu aṣọ na nitoripe ọpọlọpọ enia ti ko mọkan ati awọn ti oye koye to nipa ọna iṣelu si o ni iṣe ijọba apapọ ninu ti ro wipe ijọba apapọ ni yio jẹ gaba lori awọn ijọba ipinlẹ-ṣugbọn ọlọla Abubakar Tafawa Balewa ti fi otitọ ijọba han gedegbe.

Nisisiyi ti Alakoso ti ṣe alaye yi, yio jẹ ohun to dara bi awọn ijọba ipinlẹ wa na ba le ba ijọba Apapọ sowọpọ gẹgẹbi o ti jẹ wipe ẹgbọn ko gbe aburo jo ni ọrọ wọn.

### KOSI ỌBỌ NI IDERE MỌ

Awọn to ku ni bẹ, ọwu ẹtu ni nwọn nwọ-owe ni o. Gẹgẹbi irohin to kan wa wipe ọkan ninu awọn akọwe ẹgbẹ to ni ijọba Oke-ọya, awọn N. P. C. sọ wipe bi Ọgbẹni Niven, (Oyinbo) to nṣe baba ẹgbẹ (President) ninu igbimọ aṣofin (House of Assembly) ilu wọn ba lọ- awọn ko ni fẹ aye ipo na fun ajeji mọ, ara wọn ni awọn yio yan si ipo na.

Eyi fihan wa pe otitọ ni owe Yoruba to sọ wipe "ẹniti o ba fi oju ano wo oku, ẹbọra yio bọ oluwarẹ l'aṣọ." Iyẹn ni wipe awọn ti a ti ero wipe awọn ni yio jẹ idina fun ati gba ominira ijọba ilẹ Nigeria, ni nwọn ti bẹrẹ si parada di igi lẹhin ọgba pẹlu wa nisisiyi

Iyẹn wu wa o.


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun ori rẹ, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Ọmọba Ṣe Nkọ'le Agba



Awọn Ọmọba meji ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọmọ ti ọba obinrin bi lasiko ti o gori ipo ọba.

Nisisiyi akọbi ọba obinrin ti a npe ni Ọmọba Charles ṣe ngoke agba. laipẹ ni nwọn sọ fun wa pe o di ọmọ ọdun mẹsan, O si ni lati lọ bẹrẹ ẹkọ ni Oxford. Aburo rẹ obinrin ti awọn npe ni Anne ni koito ilewe lọ.

## Awọn ima pataki ti o jẹ nilu Eko pa kini

Nigbati awọn ara ilu Eko ba npitan, nwọn o ma fi akoko awọn ina nwọnyi juwe asiko igbati nkan ti wọn nsọrọ le lori ṣelẹ.

Ina Ayọrun bo-1859.
" Ebute Ero kini, eyi ti o jo Ṣọṣi-1868
" Fetade rita Akinni, Arugbo kan jona sile, -1870
" Oko Awo-1873
" Isalẹ-gangan-1873
" Popo Imaro - 1873
" Odunlami - 1875
" Tinubu - 1873
" Marina - 1873
" Oke-popo - 1874
" Ebute Alakoro ,,
" Ebute Ero keji ,,
" Kakawa - 1875
" Ita Ṣita, ninu eyiti Moṣalasi jona 1875
" Ita Agarawu - 1876
" ,, Bamgbose - ,,
" Okun Alasia 1877
" Ọbun Eko ,,
" Ẹpẹtẹdo ,,
Ina Hotọnu - 1878
" Apọngbọn titi lo de ita Balogun 1878.
Iyoku di ọsẹ ti o mbọ .

## Ijoba Iwo Orun Fi Ase Si Oye Jije

IBADAN. Ijọba ati igbimọ agbegbe Iwọ-Orun ile Nigeria ti fi aṣẹ si yiyan awọn enia awọnyi gẹgẹbi ijoye ilu

Ijọba ti fi aṣẹ si yiyan Ọgbẹni Ọgbeni Adeda Okose lati jẹ oye ọba A'laṣe lu Ilaṣe ni apa ile awọn Ẹgbado. Ati J. O. Adeniran lati jẹ oye Balogun ilu Ẹdẹ ni apa ile agbegbe Odo Ọṣun. Enikeran ni James Oke lati joye Onirun ilu Irun ni agbegbe Ifelodun Ọṣun

Gbigba ti ijọba gba wọn gẹgẹbi ijoye titun jẹ gẹgẹbi ofin ti sọ tẹlẹ ti a si tẹle. Ade a pe lori bata a pẹ lẹsẹ.

## AKIYESI PATAKI

**Enikeni ti o ba fe ra Iwe Irohin Eleti - Ofe Ki o lo si Idi Moto, Ogunpa, Tabi Lodo Asoju Wa, Ni 107, Oke Adi, l'egbe Sosi Aguda Nilu Ibadan.**





## Awon Gbajumo enia gba...

Ẹ ṣeun — Emi yio ra Star si. Bia na ma a nfun ni ni itẹlọrun pọ! Gbogbo awọn ti nwọn wa bẹ wa wo ni nwọn gba pe STAR BEER dara pupọ, o nwo bi titun, o si dara gan an ni. O tun nfẹ omiran bi?

### OTI

# STAR



STAR BEER dara pọ Oti ti o nwo iwo titun ti nwọn si fi eroja ti yio ma a fi ra soke ṣe ni. Awọ re wọ ni l'oju, Oorun rẹ gbadun pupọ. Awọn ẹrọ-iṣẹ ti o dara pọ ni nwọn fi npo eroja rẹ pọ.



**l'o je eyiti o dara ju!**

**Beni Sammy Sparkle wi.**


## Jesu sise iyanu ni Osiele

ABEOKUTA. Okunrin dereba kan ti o wa ninu ijo Aladura eniti gbogbo enia mo ti nwon si npe ni Jesu Gbamila, gbe moto re duro si Ogunpa nilu Ibadan, nigbati olowo re ranse si wipe, ko gbodo gba ero, ko gbodo ko eru, ki o sa wa ba on ni Ile Faranse ni Ehingbeti ni agogo meji ojo.

A gbo wipe nigbati Jesu Gbamila gba Ise na, o sare lo sije adura o si gbadura bayi pe, Jesu Gbamila, o dowo re, mo nlo si Eko

Ni on ati omo Ijeka kan ba bere irin ajo lo si Eko, Bi o ti nkoja lo ninu Igbo Osiele, nse ni owo re ju moto na si lo fi ori so igi sugbon Dereba ati omo Ijeka ye.

Moto ti o mbo lehin si gbe won lo si Ile Alaisan Abeokuta. Bi Dereba yi ti bo sile beni okunrin kan pe wipe Jesu Gbamila lesekanna, iye re soji.

O si bere si ke Haliluya Jesu Gbamila, o bere jile awon Serafu nwon fi han a, o pe gbogbo awon enia to lati rohin ohun ti Jesu se fun, Eyi ni orin ti nwon nko ninu ile adura ti ariwo Iye ati Haliluya gbode kan.

Orin :- Iku re koja lo
Iye re o iku fo!

Dereba gbekele oruko re Jesu si Gbamila, nitoto Jesu gba la, Gbekele Oluwa ki o si ma serere nitori igbekele enia asan ni.

# Etutu Ati Ebọ Nile Yoruba

1. Ẹniti o ba nwa ọmọ lat bi, yio lọ bọ orişa Iori, tabi Korikoto.
2. Ẹniti o ba nfẹ owo ati Dukia, yio lọ bọ orişa Aje.
3. Ẹniti o ba nfẹ agbara, ki o lọ bọ Orişa Oke.
4. Ọba tabi Ijoye ti o nfẹ alafia ni igba rẹ, ki o lọ bọ Ọbalufọn.
5. Ẹniti o ba nfẹ owo pupọ ki o bọ Olokun, Ọlọsa Iyemaja ati Ọşun, eyikeyi ti o ba fẹ.
6. Ọdẹ ti ko ba ri ẹran pa, ki o bọ, Orişa Ogun, Ọranmiyan, Ọşọşi Uja ati Iku-ni-gbogbo.
7. Ẹniti o ba fẹ wadi ọrọ, ki o lọ da Ifa, ẹniti o ba si fẹ wadi ọrọ, ki o lọ da Ifa, ẹniti o ba si fẹ Rara tabi Ewi, ki o rubọ si Erinlẹ.
8. Ẹniti o ba fẹ ranti oku rẹ ki o ṣe Egungun, Magbo, Gẹlẹdẹ, Jigbo, Epa, ati bẹbẹ
9. Ẹniti o ba fẹ şe etutu ki ala'şẹ ma ku, yio rubọ ẹran agbo, tabi aguntan.
10 Ẹni ba fẹ rubọ fun ẹmi gigun, yio pa aja.
11 Ẹbọ fun alafia ati ara lile Etutu Obukọ, Akukọ.
12 Ẹbọ abo kuro lọwọ ofo nile ati l'oko – Ẹnyin adiẹ.
13 Etutu ki a le bori wahala ati iyọnu Okete
14 Etutu kuro lọwọ aduarunmọ Eiyẹle ati ẹran
15 Etutu fun ki ojo le rọ Akan aruṣa
16 Etutu bi ojo ba pọju tabi ki a le bori ọta Igbin
17 Etutu abo kuro lọwọ ẹru ina ati ogun, ori Imado tabi Pẹpẹiyẹ
18 Etutu ki a le şegun ninu ogun, Obukọ Agbo Akuko
19 Etutu ki a ma ri iku ọmọde - Oromu adiẹ.
20 Etutu ki a ma ri iku aya Agbebọ adiẹ
21 Etutu bi a fẹ joye nla Imado tabi Ẹlẹdẹ.

# Oyinbo Kan Fi Oni Alapako Han Nilu Oyinbo

A gbọ irohin wipe oyinbo kan ti o nşişẹ nilẹ wa labẹ awọn oyinbo Onina (E C N) tilẹ Nigeria, ti o ti gba isinmi lọ si Kotọnu nibẹ lo gbe ri awọn ara ilu na ti nwọn nfi ọni alapako şere loju omi, O kọ gẹgẹbi nwọn ti nşe lẹ na, ki o to pada lọ silu rẹ fun isinmi.

Nigbati o pada de ilu rẹ o wa şe ikede wipe on yio fi ọni alapako wẹ okun English Channel sọda. Ọpọ awọn enia ti ko ri Ọni alapako ri ni o fẹ ri bi a tişe ndira rẹ

Ọni Alapako ti awọn ara Ajaşẹ ma fi ngbe enia lọ ta lẹru nwọn kon ori gẹgẹbi keji tabi Abawun ajapa nipa bayi nwọn a ma rin lori omi. Bi nwọn ba ko sinu rẹ apa yio yọ ẹsẹ yio yọ oluwa rẹ yio wa dabi Awun Okun.

# Kid Bassey Yio Ja Losu To mbo



Ogbeni Hogan Kid Bassey, omo ile Nigeria kan, "Abese - kun - bi - ojo" ti a koiti ri oyinbo kan ti o le gba ese kan re duro, on ni eniti o ja, ja, ja, ti o si joye oba awon kanse-kanse nigbogbo aiye fun iru awon ti o je isowo tire.

Nisisiyi Bassey ti ja, o si ti molu. ko si eniti o laiya ni iru awon egbe tire to le ko o loju mo ayafi awon ti o ba fe fi ara re joye aluki ti o ba fe danrawo.

Ọkunrin kan ara ilẹ Faranse lo tun şeleri wipe ninu oşu October, on tilẹ fẹ danrawo pẹlu Ọgbẹni Bassey na, ati wipe ija ti on fẹ ba ja yi ko nşe lati fi ba du oye. Bi on ba şişẹ, bi ara on tilẹ gba ẹsẹ rẹ si nigbana ni on yio şeşe wa ba du oye.

# Oro Oloye Akintola Nile Igbimo

(O bẹrẹ loju ewe keta)

lori ete ati ero ati igbagbọ kan na wipe lọjọ keji oşu April 1960, a o gba ominira ara wa a o si bọ ajaga asingba silẹ.


## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun German to şeşẹ de, fun oniruru aisan tokuta tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.


## Lagos Executive Development Board

### Akiyesi Fun Awon Awonle Ati Awon Akole

A fi iwe yi kede fun gbogbo awọn Awonlẹ ati awọn Akọle wipe ki nwọn to bẹrẹ si şe eto ilẹ wiwọn tabi ile kikọ nilu Eko, wọn nilati wa şe alaye rẹ nile işẹ Igbimọ Town Planning şiwaju.

Pupọ ni awọn ile ti nwọn nkọ si laigbaşẹ ijọba ati ọpọlọpọ ninu awọn ile na ni awọn ti o ni wọn ti wọn ilẹ wọn ti nwọn si ti gba imọran awọn to mọ nipa ile kikọ.

Inu igbimọ yio dun bi awọn Awonlẹ ati awọn Akọle ba le sowọpọ pẹlu wa lori ọrọ ile kikọ ati ilẹ wiwọn nilu Eko yi.

**J.W. Henderson**
Chief Executive Officer

## Sode omo ilewe kan pa ... re

[I]BAN.– A gbọ pohin ... e odomọmọ ... undia ti o nkọ ẹkọ ninu ... we gig University ... ge Ibadan, ni wọn ... ti o ku sinu ile ọrẹ rẹ okunrin. Orukọ ọmọbi na ni Bisi Fagbenle, orukọ ọmọkunrin ni Benedict Obumselu.

Nigbati awọn o jogbọn ṣe iwadi nipa ọrọ yi, nwọn fi ọrọ na le awọn ọlọpa lọwọ. Ẹsun ti nwọn fi ọdaran yi sun (Benedict Obumselu) ni wipe, Iwọ mọ wipe Bisi Fagbenle, ti o nṣe ọkan ninu awọn ọmọbinrin ti o nkọ ẹkọ ninu ilewe University Ibadan, gbero lati huwa ti ko dara nipa wipe o fẹ ṣe oyun pẹlu agbara, eyiti o lodi si ofin ti iwọ ko si ronu wo nipa ṣiṣe eyi, ki o ba le gba ẹmi rẹ la, asẹhinwa asẹhinbọ, o ṣẹsi ofin.

Awọn lọya mẹta lo fẹ gbẹjọ Benedict Obumselu ro, G. C. Onyiuke, B. Olowofoyeku ati Olu Ayọọla. Adajọ yẹ ẹjọ na si ọjọ 27th oṣu Sept 1957 Adajọ gba iduro rẹ lori ogorun Pọun. Enia marun lo fẹ jẹri fun ọlọpa.

## Eyie Okin Ni Arewa Eiye

(O bẹrẹ loju ewe keji)

Nigbati tolo-tolo ba fẹ yiabọn idi, yio tu irere idi rẹ kan gẹgẹbi abẹbẹ, bayi gẹgẹ ni ẹiyẹ Ọkin nṣe. Nigbati Ọkin ba tu irere idi rẹ ka, ẹwa rẹ yio pọ, ko si oriṣi awọ kan ti iwọ ko ni ri ni ara rẹ tan Iwọ yio ri dudu pupa ofefe aywọ̀n koronu Olodunku Onikoko ati oriṣi riṣi awọ bawọnni. Ko nṣe wipe iru eiyẹ yi ko si nilẹ Yoruba, o mbẹ ṣugbọn o ṣọwọn gidigidi gẹgẹbi ẹiye Kara kara funfun ti ṣọwọn. Orukọ ti Yoruba npe ni Ọkin. Awọn Ẹgba npe ni Ẹiyẹ Oniyekiye awọn Eko npe ni Ẹiyẹ ile Payne nitoripe Dadi Payne lo kọkọ mu iru eiyẹ yi wa si Eko.

Awọn iyẹ ti ao tun ma sọrọ rẹ nigbati miran ni eiye Akala eiye Atọka eiye Agbigbo. Ohun kan ti o ya ni lenu nipa eiye yi ni wipe nibikibi ti eiye Ọkin ba gbe wa o ko ni gbuto ejo lọtun losi niwọn ogoji ese ibiti o gbe wa. Pelupelu ni agbegbe ibiti awọn ejo ba pọ si ti a fi ive eiye Ọkin le ori ese ina, nṣe ni oorun re yio le nwọn rin jinna si agbegbe na.

INFLUENZA

Ohun ti o le gba o kuro lowo amodi nipe ki o ni alafia ara.



Ki enia ri orun sun daradara lo je pataki iranlowo fun ara lile.

Eyi nidi rẹ ti Ovaltine ṣe dara ni mimu, yio jẹki o sun fọnfọn fun isinmi igbadun ni alalẹ. Atipe Ovaltine si kun fun awọn onjẹ atata, ti ara rẹ nfẹ fun agbara lati le fi ṣẹgun aisan. Mu Ovaltine ni alẹ yi ati ni alalẹ fun igbadun ati alafia ara rẹ.

Tete ri alafia, bi aisun Influenza ba kọlu ọ, jẹki Ovaltine fun ọ lagbara rẹ pada, awọn nkan ti afi ṣe ni:-



Ẹyin adiẹ, irugbin ati Wara pẹlu eroja marale, gbogbo wọn ni a papọ sinu Ovaltine ti o fi jẹki o nfun ọ ni alafia ati ara lile.

OVALTINE



Dara fun isinmi igbadun ati ara lile.

# Oro Prime Minister Niba Soki

Ọjọ ola ni ọjọ oni yi je fun gbogbo ile Nigeria nitoripe o je irin ajo ikehin si ọdun idande wa o si ye pe ki gbogbo wa ti o mbe nihin loni dupe lọwọ Olodumare ti o da wa si lati ri ọjọ oni yi.

Ni iwọn ọdun meta si so de ogogoro ohun ti gbogbo wa ti nreti lati ọdun si ọdun fun ominira latigba ti a ti bọ si abe aṣe ijọba Gesi niwọn ọdun merindilọgọrun



Alhaji Tafawa Balewa

ọpọlọpọ iṣelẹ lo ti ṣẹle ni ọdun 1861 wa titi di oni ọdun na ni a gbe ijọba ilu Eko le Ijọba Gesi lọwọ ati ni ọdun 1957 ni ile agbegbe Iwọ-Orun ati Ila-Orun di Ominira.

Awọn enia dudu ti rin jinna o si ye ki ayin ara wa wipe, lati iwọn ọdun merinlelọgbọn ti a ti mba wọn ṣe igbimọ, awa na papaa de aye ti a wa loni yi. Nitoripe igbimọ aṣofin ti a da silẹ ni ọdun 1923 eyiti o ṣe akoso wa titi di opin ọdun 1951 lo fi ipẹ wa le ọna yi.

O yẹ ki a fi ọpẹ gidigidi fun awọn enia wa ti o ti ku, tabi ti o mbẹ laye ti o ṣe gudu-gudu meje nipa ilọsiwaju ilu wa iyi, eyiti a njẹ anfani rẹ loni.

Ni ọdun 1952 ni akọkọ yan awọn enia dudu sinu ipo Minister, ibẹ ni a gbe kọkọ bẹrẹ iṣẹ ijọba ilu wa.

O tọ, o si yẹ ki a ma ri si ero ti olukuluku enia ba mu wa nipa gẹgẹbi orişirişi ẹya enia ti wa nilẹyi.

Irẹpọ ni ohun ti o si yẹ wa ni wipe ki a sagbara wa ki ijọba Eko yi tumbọ lagbara siwaju a ti fi agbara nla le wa lọwọ, nwọn nwọn si nfẹ wo inu ara ti a ma fi ilu Eko da latinu eyi ni nwọn o ti mọ gẹgẹbi a ti le kapa ijọba ara wa si.

Iṣẹ nla ti o mbẹ niwaju wa ni wipe ki a ṣiṣẹ iṣelu na de ipo ti ao fi ka wa si ẹniti o yẹ lati gba ominira ni ọjọ keji oṣu April, 1960.

O yẹ ki gbogbo enia mọ pe, iṣẹ nla ni iṣẹ na ko si nṣe ohun ti o rọrun. Ko nṣe ọrun awọn Ministers ti o wa ninu igbimọ (Representative) nikan ni ẹru na wa, ṣugbọn o mbẹ lọrun awọn Ministers gbogbo ti o mbẹ ninu ijọba Iwọ-Orun, Ijọba Ila-Orun ati ijọba Ilẹ Hausa pẹlu ti nwọn mbẹ ni inu igbimọ. (Assembly.)

Ni kukuru, iṣẹ na tun mbẹ lori gbogbo enia ti o mbẹ ni ilẹ Nigeria, nitoripe bi ẹnikọkan ba ti sagbara to, ni yio fi jẹki a tete gba ominira ni ọdun 1960.

# Ero Lena Ilu Oyinbo

Lọsẹ to kọja lọ ni ni Ọgbẹni M. A. Araniloye ba ọkọ ofurufu fo lọ silu Oyinbo.

Gbogbo awọn ọrẹ, ibatan ati awọn ojulumọ lọ wa ba yọ ayọ idagbere. Diẹ ninu awọn enia ti a le daruko ni Ọgbẹni M. Adeniyi, D. A. Aweyale, C. Adekẹyẹ. B. Atolagbe, R. Ologunde, T. A. Taiwo S. O. Adeoti.

Awọn Omidan, D. J. Ọdẹtundun ati H. R. Ibiyẹyẹ. O dabọ o, ọkọ a refo o.

## Lehin Ogorun Odun, Orori Martin Yipo Pada

(O bẹrẹ loju ewe kini)

oju Orori na wa ni ode gbangba ni wipe nigbati awọn kọkọ wo'le nilu Eko lati fi lana fun oju ọna mọto, ni nwọn ti mọ ogiri s'oju orori lati mọ ibẹ siyatọ.

A gbọ wipe Daddy Ojo Martins ku nigbati o di ẹni ọgọrin ọdun, ati wipe, o di ọgọrun ọdun ti o fi ile aiye silẹ, iyen ni wipe a bi i ninu ọdun 1777.


## Lati fun o lokun-inu ati agbara re pada

Lẹhin

AMODI INFLUENZA

lo egbogi

**Hommel's Haematogen**

pẹlu Wara tabi Ọti Waini fun ọsẹ kan tabi meji

A le rira ni Ṣọbu ti nwọn nta egbogi ati ni gbogbo ile itaja

ALAKOSO EGBOGI NA NI-

**ALBAN PHARMACY LTD.**

2, VICTORIA STREET,

Lagos.



No. 132

## VACANCIES FOR ASSISTANT Superintendent of Police (Works)

Applications are invited from suitably qualified Nigerians for appointment as Assistant Superintendents of Police (Works) in the Nigeria Police Force.

Particulars of this posts are in Government Notice No. 1580 (2nd publication) in the Federation of Nigeria Official Gazette of the 5th September, 1957.

Applications should be addressed to the Secretary, Federal Public Service Commission, Lagos, so as to reach him not later than 30th September, 1957.



# M.B.T.

(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. ... dé, òkùnrùn ... lọ. ... òyì pòsèsè. Àlá búburú ... àìlèsùn ... M.B.T. ... ẹ̀jẹ̀ ... amú ni ... àkèrè. ... pàwọn abiyamọ. ... àti àìyà-jíjá ...

ARADAN STORES P.O.Box 2 EBUTE-METTA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 23590